# ỌDỌ - AGUTAN ỌLỌRUN

## Ifihan 5:1-14

## ẸKỌ 461 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Johannu ri Jesu mbọ̀ wá sọdọ rẹ̀; o wipe, Wò o, Ọdọ-agutan Ọlọrun, ẹniti o kó ẹ̀ṣẹ aiye lọ!" (Johannu 1:29).**

**Ọdọ-Agutan Ọlọrun**

Kristi di "Ọdọ-agutan Ọlọrun" ni tootọ nigba ti O ku lori igi agbelebu. A ti yan An lati jẹ́ "Ọdọ-agutan" naa lati ipilẹṣẹ ayé wá.

Ẹ̀ṣẹ eniyan ti buru pupọ, o si buru sibẹ nisisiyii niwaju Ọlọrun to bẹẹ gẹ ti o fi jẹ pe ikú Ọmọ Ọlọrun nikan ṣoṣo lori Oke Kalfari ni o le ra ọkan ti o ti sọnu pada. O ta Ẹ̀jẹ Rẹ̀ silẹ lati wẹ ẹ̀ṣẹ awọn wọnni ti wọn ba ronupiwada patapata nù. "Nitoriti a ti pa ọ, iwọ si ti fi ẹ̀jẹ rẹ ṣe ìrapada enia si Ọlọrun lati inu ẹyà gbogbo, ati ède gbogbo, ati inu enia gbogbo, ati orilẹ-ède gbogbo wá" (Ifihan 5:9).

Bawo ni o ṣe yẹ fun ọkàn wa lati kún fun ọpẹ to pe Ọlọrun le rán Ọmọ Rẹ̀ kan ṣoṣo lati kú fun ẹ̀ṣẹ wa ati lati tun jinde fun idalare wa! Awa, ti a ti jẹ́ ẹlẹṣẹ, ni irubọ "Ọdọ-agutan" ti o pé lọnakọna, ti to fun wa!

**Itẹ́ Ọlọrun**

Bi Johannu ti n wo ọpọlọpọ awọn ohun iyanu nì ní Ọjọ Oluwa, lori adado Erekuṣù Patmo, o ri Itẹ́ Ọlọrun ati Ẹni kan ti O joko lori Itẹ́ naa. O lẹwa pupọ O si n dán, bi okuta iyebiye. Yika ori Itẹ́ yii ni oṣumare kan wà. Awọn agbaagba mẹrinlelogun ti a wọ laṣọ funfun joko yi Itẹ́ naa ká; pẹlu ade wura ni ori wọn.

Bawo ni Johannu, ẹni ti a lé kuro laaarin awọn eniyan, yoo ti ro ara rẹ̀ si ẹni irẹlẹ to lati ri ogo Itẹ́ Ọlọrun funra rẹ̀! Iru ọla wo ni o pọ to yii ti a fi fun eniyan ẹlẹran ara!

Lati igba de igba ni awọn agbaagba wọnni maa n foribalẹ fun Ẹni ti O joko si ori Itẹ́ naa, lai ṣiyemeji, Ẹni naa ni Ọlọrun Baba. Wọn a si fi ade wọn lelẹ niwaju Itẹ́ naa, wọn a si wi pe, "Oluwa, iwọ li o yẹ lati gbà ogo ati ọlá ati agbara: nitoripe iwọ li o dá ohun gbogbo, ati nitori ifẹ inu rẹ ni nwọn fi wà ti a si dá wọn" (Ifihan 4:11).

**Iwe ti a fi Edidi Dí**

Lọwọ ọtun Ọlọrun lori Itẹ́ ni Iwe kan wà, ti a kọ ninu ati lẹyin. A fi edidi meje dí Iwe naa.

Gẹgẹ bi Johannu ti n wò, angẹli alagbara kan fi ohùn rara kigbe pe, "Tali o yẹ lati ṣí iwe na, ati lati tú èdidi rẹ̀?" (Ifihan 5:2).

Ko si ẹni kan ni ayé tabi ni Ọrun ti o yẹ lati ṣí ati lati ka Iwe naa – tabi lati wo inu rẹ̀ paapaa. Johannu sọkun pupọ nigba ti ko si ẹni kan ninu awọn eniyan ti o le ṣi Iwe naa. Njẹ iwọ ti sọkun ri lati mọ ifẹ Ọlọrun, lẹyin naa ki o si yọ̀ nigba ti O ba fi ifẹ Rẹ̀ hàn gbangba fun ọ?

Bi Johannu ti n sọkun, ọ̀kan ninu awọn agbaagba naa wi fun un pe, "Máṣe sọkun: kiyesi i, Kiniun ẹ̀ya Juda, Gbòngbo Dafidi, ti bori lati ṣí iwe na, ati lati tú èdidi rẹ̀ mejeje" (Ifihan 5:5).

**Iyin si Ọdọ-Agutan**

Johannu ri Jesu bi Ọdọ-Agutan ti a ti pa ti O duro ni aarin Itẹ́ naa laarin awọn agbaagba wọnni. O wá O si gba Iwe naa lọwọ Ẹni ti o joko lori Itẹ́ naa. Gbogbo wọn si kun fun ayọ̀ ati iyin. Awọn agbaagba mẹrinlelogun naa wolẹ lati sin In. Gbogbo wọn ni wọn ni harpu wura, ati aago wura ti o kún fun turari, ti i ṣe adura awọn eniyan mimọ́. Ronu le eyi! Pe o ṣe e ṣe ki adura atọkanwa rẹ ni idapọ pẹlu isin iyin ogo si Oluwa! Bi awọn agbaagba wọnni ti wolẹ lati sìn, wọn kọ orin titun kan bayii pe, "Iwọ li o yẹ lati gbà iwe na, ati lati ṣí èdidi rẹ: … iwọ si ti ṣe wọn li ọba ati alufa si Ọlọrun wa: nwọn si njọba lori ilẹ aiye" (Ifihan 5:9, 10).

Lai ṣe aniani, awọn agbaagba mẹrinlelogun wọnni ni wọn duro fun awọn ayanfẹ ti a ti palarada, gẹgẹ bi a ti gbà wọ́n là lati inu eniyan gbogbo ati orilẹ-ede gbogbo. Wọn o jọba lori ilẹ ayé, eyi ni ileri ti a ṣe fun awọn ayanfẹ ti wọn yoo goke lọ lati pade Oluwa ni igba Ipalarada. Wọn yoo ba A pada, wọn yoo si ba A jọba nihin lori ilẹ ayé yii fun ẹgbẹrun ọdun (Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun).

Ta ni ko ni fẹ kọrin iyin ogo Ọlọrun pẹlu ireti bi iru eyi? Onigbagbọ́ jẹ ẹni ti inu rẹ̀ maa n dùn nigba gbogbo; nigba miiran o maa n ri itọwo awọn ohun ọrun gbà, o si ni ireti lati ri Jesu ati lati ba A jọba.

Bi awọn agbaagba wọnni ti kọrin, ohùn awọn angẹli pupọ ati ọgọọrọ awọn ẹni irapada ti a ko le kà iye wọn dara pọ̀ mọ wọn, wọn si n wi pe, “Yiyẹ li Ọdọ-Agutan na ti a ti pa, lati gbà agbara, ati ọrọ̀, ati ọgbọ́n, ati ipá, ati ọlá, ati ogo, ati ibukún” (Ifihan 5:12). Nigba naa ni gbogbo ayé dabi ẹni pe wọn dara pọ̀ pẹlu wọn ni yiyin Ọdọ-Agutan naa.

**Ailera Eniyan**

Bawo ni orin wa ati iyin wa ti o dara jù lọ nisisiyii ti jẹ alailera ati alaito to bi a ba fi wé iran nla ti Johannu ri! Bi gbogbo ogun ọrun ba parapọ̀ ni yiyin Ọdọ-Agutan Ọlọrun, ki ni ṣe ti awọn ọkunrin, obinrin, ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin kò fi ogo ti o yẹ fun Ọlọrun fun Un ni akoko yii? Awọn ti wọn jẹ́ Onigbagbọ́ n gbiyanju lati yin Ọlọrun logo, ṣugbọn ọpọlọpọ igba ni ki i ṣe e ṣe fun wọn lati le sọ ni kikún nipa gbogbo ayọ̀ ọkàn wọn. Awọn ti wọn ki i ṣe Onigbagbọ́ kuna lati ri oore ati ogo Ọlọrun.

Igba kan n bọ̀ nigba ti gbogbo eniyan yoo fi eekun wọn kunlẹ fun Ọlọrun (Isaiah 45:23). Kò ni si ayọ̀ ati ireti ologo fun ẹni ti a fi ipá mú lati fi eekun rẹ̀ kunlẹ ati lati sin. Ifoya ati ẹ̀ru ni yoo wà fun un, yoo si mọ̀ pe oun ti sọ ẹmi oun nù, ati pe oun ni ipin ninu ikú keji, a si ti ké oun kuro lọdọ Ọlọrun lae ati laelae.

Ẹ jẹ ki a ṣe afẹri, ki a si sin, ki a bu ọlá fun, ki a si juba Kristi, Ọdọ-Agutan nì, Olugbala wa ọwọn. Ẹ jẹ ki a fi ayé wa fun Un, ati talẹnti wa; ẹ jẹ ki a kọrin ki a si yin In. Ẹ jẹ ki a lakaka lati pẹlu awọn wọnni ti yoo pada pẹlu Rẹ̀ lati ṣe akoso ati lati jọba bi awọn ọba ati alufaa lori ilẹ ayé yii fun ẹgbẹrun ọdun, lẹyin naa ki a si wà pẹlu Rẹ̀ titi ayeraye.

**AWỌN IBEERE**

1 Nigba wo ni a yan Jesu lati jẹ́ Ọdọ-Agutan Ọlọrun?
2 Ki ni awọn ọrọ Johannu Baptisti nipa Jesu gẹgẹ bi Ọdọ-Agutan Ọlọrun?
3 Ṣe apejuwe Iwe naa ti o wà ni ọwọ ọtun Ẹni ti o joko lori Itẹ́ nì.
4 Ta ni wọn n wá lati ṣí Iwe naa?
5 Ki ni ọ̀kan ninu awọn agbaagba nì sọ fun Johannu bi o ti n sọkun?
6 Ki ni awọn ago ti o kún fun turari?
7 Ki ni awọn agbaagba wọnni ṣe nigba ti Ọdọ-Agutan nì gba Iwe naa?
8 Njẹ awọn angẹli paapaa ràn wọn lọwọ lati kọ orin titun naa? Ki ni ṣe?
9 Aṣoju awọn wo ni awọn agbaagba wọnni i ṣe?